IWADI IKU TO PA ALHAJI ADEGOKE ADELABU

Ogun Ita'ja

E Polowo oja yin sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe, Kia L'oja o ta.

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

6th & 7th BOOKS OF MOSES
LEDE YORUBA
15/-
A LE RI IWE YI RA NI OSHODI COMMERCIAL SERVICE
56, KING GEORGE AVENUE YABA
ATI NI
131, IDIKAN ROAD IBADAN

VOL. X No. 574. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, MAY 31, 1958. KOBO MEJI (2d)

# Iwadi Iku To Pa Alhaji Adegoke Adelabu

IBADAN. Ni ojo Atajata (Tuesday) ose yi ti ise ojo ketadinlogbon osu yi ni niro ojo iwadi iku ti o pa Alhaji Adegoke Adelabu ti ise Asiwaju ijo Alatako ninu Igbimo Asofin Iwo-Orun ati Alaga osise igbimo egbe N.C.N.C. ni ipinle Iwo-Orun bere nilu Ibadan eniti o se agbako jamba moto l'ona Ode Remo nitosi ilu Shagamu l'ona Ibadan ni ojo k'edogbon osu March, 1958.

Awon Loya Mojid Agbaje, R.A. Akinyemi, B.O. Fakayode Kehinde Sofola R.O Akinjide B O Esan ati A Adisa l'owa fun awon ebi Adelabu. Ogbeni S O Lambo l'o wa fun Albert Younan, oyinbo Kora ti o wa moto ti Alhaji Adelabu wo.

Ogbeni T.A.B. Oki l'o wa fun Ijoba.

Eniti o ko jeri ni Dokita Adesanya to wa nile Iwosan ilu Shagamu O so ninu eri re pe ou ye oku Adelabu wo, on si ri wipe gbogbo egbe to wa lara re je eyiti moto da si lara, ko si ogbe ibon lara re. Lehin eri re ni Loya Lambo bere ase lati bere oro lowo eleri sugbon Loya Agbaje tako, fun nkan bi wakati kan ni awon fi fa oro na ki Oluwadi to ba won d'ero si.


ALHAJI ADEGOKE ADELABU

Dokita Eze-Ashi ti University College. David Ogunbo Olopa Ode Remo ati Ogbeni Olanusi Eboda ti ile re wa nitosi ibiti jamba na gbe sele ni nwon tun jeri eniti o jeri gbehin ni Raimi Amao olopa to ngun moto alupupu.

Awon enia ti o tun jeri ni Oga Olopa ilu Shagamu Ogbeni S. Abereoja Ogbeni R.A Kirry (A S P) Oga Olopa ninu eri won a awon ti so pe ere ti awon moto mejeji to kolu rawon ti po ju.

Ogbeni Alan Stephenson okan ninu awon oyinbo meji to wa ninu moto ti o nti ona Ibadan bo so wipe on ko mo igbati jamba na se nitoripe on ti sun fonfon ni Ile Iwosan nilu Shagamu ni on gbe taji on ti daku lati oju orun sugbon ki on to sun Dereba to awa moto ti awon nrin bi adota si ogota ibuso fun wakati kan

Oyinbo Kora to wa Moto ti Alhaji Adegoke Adelabu fi ku si nu r ati Adeleke Atanda to a Moto keji l'o jeri. O Albert Younan, O inb Kora so wipe ore tim timo ni on pelu Ol gb Alhaji Adelabu, ise owo else (Trader) si wa larin awon mejeji, ti o je iso olowo giriimoyan. O so pe Alhaji Adelabu kigbe pe ki on wo Moto to mbo lokankan awon yi I on papa si ti ri moto na lokere pe okankan Mot ti awon ni o nsare b pelu ere sisa buraku ni moto na fi kolu ti on.

Adeleke Atanda so pe moto ti on ko sare ju 40 tabi 45 ibuso lo sugbon Oyinbo to wa ninu moto re so pe o nsare to 50 tabi 60 ibuso siwaju.

Bi awon ba ti pari oro iwadi na si ao te irohin re fun yin ni ose to mbo bi Oluwa ba fe,

THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited.

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital - £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria.
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS, NIGERIA

22 Branches throughout Nigeria including
IBADAN ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO ILESHA, ILARO, BENIN-CITY, WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.

LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell

Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams: Natbaniger, London.
Head Office Representative in London.
Ernest Olubunmi Obasa—Porter
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG

# Electricity Corporation of Nigeria

## Public Notice

### Wiring Of Premisses For A Supply Of Electricity.

Prospective consumers who are contemplating having their premises wired for connection to the public electricity supply and existing consumers who wish to extend their wiring installation are advised that the Electricity Corporation may decline to connect any installation which has been wired or extended without full compliance with Regulation 203 of the Electrical Supply Regulations.

The provisions of Regulation 203 are as follows:-

"203. [1] For the purpose of ensuring that the requirements of the Electrical Supply Regulations and of the Electrical Wiring Regulations are being complied with, the Electricity Corporation of Nigeria shall require every consumer and/or prospective consumer to serve upon the Corporattion notice of:-

[a] the consumer's intention to instal or have installed electric lines, wires, fittings, apparatus and appliances on any premises;

[b] the consumer's intention to make or have made any additions or alterations to his present installations."

(2) The consumer shall render the Eectricity Corporation of Nigeria every reasonable facility for inspecting and testing such electric lines, wires, fittings, apparatus and appliances during the progress of the work and on its completion.

In giving notice of the necessity for compliance with Regulation 203, the Electricity Corporation wishes to point out that such compliance is not only legally necessary but is in the mutual interest of the Consumer and of the Corporation.

ARTHUR FAUL
Secretary to the Corporation

24th May, 1958.

# Olopa Onifere Nilu Oyinbo



Eniti a nwo nian aworan yi ni Ogbeni kan ara ilẹ Ghana ti oruko re nje Joshua K. Tawia, ọkan lo je nian awọn ọlọpa onifere ile Ghana.

Aworan re yi ni igba ti o lọ ko iṣe olori awọn afunfere fun ọdun meta nilu Oyinbo fere ti o si gbe dani ti o nfun yi je eyiti o tobi ju ninu awọn ohun elo ti awọn fi akọrin.

## Obinrin Kan Sonu Fun Odun Mokandilogun

Oke Ọya. Irohin ti a gbọ ni wipe ọmọde-binrin ọmọ Yoruba kan ti o ngbe ọdọ awọn ibatan re nilu Jos lo lọ ki agbon nigbati o pade ebanna Hausa kana ti o sọ fun pe on yio mulọ sọdọ baba rẹ ni Kaduna wo mi na enikeji ọrọ na ko le dun ni jeki a bere lọwọ ọlọrọ.

Ọmọbinrin na nrojo fun Ọlọpa o wipe nigbati o sọ pe on yio mu mi lọ sọdọ baba mi jau mi dun mo ni tele lehin lo ba mu mi lọ si abule kan nitosi ilu Jos ti nwọn pe ni Wamba. Nibe ni on pelu baba na ngbe titi on fi to eni ọkọ awọn si fi on se iyawo fun Malam Garuba Hausa kan.

Nigbogbo igba ti mo fi wa lọdọ Garuba mo je sanku fun lodo re gugbon oko ri aye sa lọ oltoripe ọmọ marun ni i on bi fun Garuba na. Nigbati o se ni mo ri aye lati sa kuro p'lu ọmọ mi abigbabia ẹmẹ odun marun.

Awon Ọlọpa bere lowo re wipe baba Hausa na ti o je gbe re nf o ba ri o le mọ? O dahun pe beni ago mo ẹsgbon baba na ti ku. Awon ijoba ile Hausa si nse iwadi nipa awon omo re merin ti o ku lodo malam Garuba.

## E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re-


ERỌ ATATA TI NGUN IRẸSI T'O SI NFẸ MỌ TONITONI
(Ancomill)

Erọ na rọrun lati lo, o si nse iṣe lasegbadun; o to gbekale, o yayi, iṣe re si buniya.

Lẹsẹkẹsẹ to ba ti da iresi onikanda si i ni yio gun u, ti yio fẹ ẹ, ti yio se ọ di funfun laulau.

LEVENTS MOTORS LTD
(Technical Dept)
Ebute Metta, Ibadan, Kano, Port Harcourt ati Aba ni ẹ ti le ri ra.


## Owo Te Ole To Ji Bata

EKO. Ọmọkunrin Hausa kan ni a gbọ wipe o lọ ko awọn ni ba'a, ti o si di igbaju, igbamu. Pelupelu ẹaun ti pọ kakiri ilu awọn Imale nipa bata kiko, bi awọn ba ti ri eniti bata re ditun dle, nwọn o ma sọ oluware nigbati o ba fi ori bale nisu irun, ki oluware to dide, owo... o ti ko bata na lọ.

[wo yoku loju ewe keje]


HAPPINESS SUPREME!




"Ma gives me "BANWO" and so, I'm strong, robust and healthy."

Buy BANWO for your baby
large bottle 5/6, small bottle 4/6.
Postage 9 extra. Ask for wholesale price.
THE ARADAN STORES P.O.Box 28 I.B
and branches

# Etutu Oku Iya Oduduwa

(APA I)

Ni ojo kan, ni asiko ile oku Iya Oduduwa ti awon Irunmole fe se etutu fun oku Iya Oduduwa Agemo wa, Kori, Egungun Orisa Oko, Jigbo, Epa, Pakoko, Majowu, Magbo, oro, Ogun, Ajantele Elekuru, Ologede, Ogunran Olumokun, Eyo, Oya, Sango ati iru awon Mole bawonni lo peju-pese si ita Oloku lati pa obi ki awon to bere etutu won.

Oduduwa mu obi ajopa kan sile o ni ki awon pa a ki awon fi se tutu. Lojo na lohun ki enikeni to se akan-ki-nkan o ni lati koko pa obi ki o fi ye wo bi ijade akan na yio ti ri. Asa na ni gbogbo awon ti o ni Mole nile ati enitl ko ni Mole nile ako ti awon fi npa obi ki awon to se akan,

Gbogbo awon Irunmole lo pa obi ti Oduduwa mu sile ti. Awon elomiran so pe igi ni obi na, omiran so pe okuta ni; gbogbo won patikari lo pa obi na ti ko si ogo asa Yoruba lati se ohun kan yala ibi ni akan na tabi ire lalmo bi apade si okan na yio ti ri. Aflepa obi yi, ko jeki awon le ma ba etutu na aise.

Oduduwa wa mu oro so o wipe:–

Riwo, riwo ma tu ariwo,
ya a,! ya a !
Eru ! O w o ! Gbingbin,
Hin-n !

...ya mi lenu lati ri wipe ...ogbo nyin bi eti ni ikimi ...i ti e si li eru jeje lara ...yi e ko le pa obi ajopa lati fi wure ! E ko ...ni ye ara n y i n wo ...si ye okan nyin wo bi a ba ri enitl o ni ...orun ki o lete tuba.

...mu awon Irunmole ...o iru oro yi si won ...Olukeluku won bere ...wo r a e s e s i ...ati ojo na wa ni ...e k i a m a rawo ...orun nigbati a ba

...u loju ewe kefa]

# Ijafara L'ewu

Onisegun ilera ilu Eko lo se ikilo yi wipe ki gbogbo awon enia ti o nje eje Sadini sora nipa jije eja Sadini kan tiko ni oruko lara ti nwon nta kiri, nitori ewu mbe ninu jije iru eja be. Bi o ba si sakiyesi panu sadini na lowo yio ri pe, nse lo wu sode ni egbe kan. Ijafara l'ewu o.





## Awon Gbajumo enia gba...

Eseun — Emi yio ra Star si. Bia na ma a afun ni ni itelorun po! Gbogbo awon ti nwon wa be wa wo ni nwon gba pe STAR BEER d a r a pupo, o nwo bi titun, o si dara gan an ni. O tun nfe omiran bi ?

OTI

# STAR



STAR BEER dara po Oti ti o nwo iwo titun ti nwon si fi eroja ti yio ma a fi ru soke se ni. Awo re wo ni Foju, O orun re gbadun pupo. Awon ero-ise ti o dara po ni nwon fi npo eroja re po.



I'o je eyiti o dara ju !
Beni Sammy Sparkle wi.

# ELETI QFE

A-NJU-WQN KO SE WI L'EJQ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - OFE LAGOS"

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. X. NO. 574. LAGOS, SATURDAY MAY 31, 1958.


## O Dabo, Oko A Refo o.

Bo pe titi, Jimo yio ku qla, ni gbolohun ti a le so si ti awon elere ile wa nihin, l'okunrin l'obinrin ti o nlo ba won sere idaraya nilu Cardiff nitoripe o to igba meji ti awon ti f'oju sona lati dide ti idide won na ko bo si.

Og'oko (Captain) ti awon ti yan lati se olutoko won lo ninu oko Ofurufu ni o se agbako jamba moto ti o f'arapa ni ojo Satide to koja, eyi l'o fa idaduro ti won ko fi le lo ni ojo ose mo, nitoripe awon ajase ni lati se eto raase fun olutoko miran lati ilu Oyinbo wa ki awon to le lo.

Ni asale ojo Tuesday ni oko ofurufu ti o ko won lo to si ni Ikeja o si ko gbogbo awon elere idaraya wa lo pelu ifokanbale wa lori won wipe awon yio jagun-mole bo wa'le. Awon akonije wa to ko won lo ni awon Ogbeni O. A Omololu V.B.V. Powell ati S. O. Jolaoso.

A fi eyi ki won pe alo a dara abo asuowon lagbara Allah.

## Imoran Fun Enyin Abiyamo


Enyin abiyamo e wa ra QMORELA o dara pupo fun awon omode.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo eebogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode

QMORELA BABY MIXTURE

(Sile Meji Abo 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lodo

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemists)

10, VICTORIA STREET, LAGOS


## Ibukun Ni Iranti Oledodo



Ni ojo Kerinlelogun osu May 1958 ni o di odun kokanla ti baba wa oninu're ti fi ile se aso bora.

Ninu awon omo to fi sile laiye ni M.A. Thompson ti ise Bank Manager ati Taju Thompson Managing Director, Iwe Irohin Eleti-Ofe.

Baba mase je okun, mase je ekolo,
ohun ti awon ba nje lode orun
ni ki o ma ba won je.
Sunre! Opomoja-alekan, Sunre!!

## Agbe Nigeria Lo ki Agbe Ghana



Awon enia ti a nwo ni apa otun yi ninu aworan ni awon agbajo egbe Agbe ile Nigeria ti a yan lati lo be awon agbe Onikoko ile Ghana wo.

Ninu aworan yi awon iko agbe Nigeria lo mbe ni apa otun ti ile Ghana lo mbe ni apa osi ti nwon da aso funfun bora. Ohun pataki ti a gbo wipe nwon lo se ni pe ki nwon fi oju si bi igi koko won ti ri, bi nwon ti ase koko ti won to fi ndara.

# Ibere Oro

Okunrin kan ti a npe ni Atere-maja lo bere oro yi lodo lemomu Ajakuta wipe. On fe ki Lemomu se itumo aditu oro yi fun on. Kini eiye keiye igi-kigi ati enia kenia?

## Idahun

Eiye-keiye ni eiye adan ti o gba enu jeun, ti o si tun nfi enu kanna yagbe re sile.

Igi kigi ni igi afomo ti ko nhu gbomgbo tire loto ayafi ori igi elegbe re. On ni Igi-kigi.

Kio wari eniti a npe ni Enia kenia ni okunrin ti ofi ile baba ati iya re sile ti o le pe ile ano re lo ngbe, on ni Enia kenia Bi oro ti je nanj.

Lemomu Ajakuta

---

# Oba Ede Se Itumo Oro Ti Ilu Gangan Nwi

A gbo irohin wipe Alaiyelawa Laoye Kini, Timi oba ilu Ede ko awon onilu Gangan medogun sodi lati ilu re, lo sile egbe Island Club nilu Eko, ni ojo Alamisi ti o koja lo fun ayeye ajodun asa ibile ti awon se nibe.

Ohun ti a gbo wipe o fi awon onilu na se ni pe awon Onilu Gangan na, nfi ilu won soro, oba na si stunmo re.

Bakanna na ni Ogbeni Fela Sowande ti o nse olori awon Akorin inu ero Radio (Asoro-magbesi) tun oro nipa awon orin ile Yoruba nibi apejo kan ti awon egbe British Council gbe kale ni ojo Jimo ti o koja ni No. 1A King George Avenue ni Yaba.

---

*Story of a Successful Trader*

# Mr. Peter Ezeli

## and The United Africa Company work together for prosperity



SINCE leaving school, Mr. Peter Ezeli has [illegible] flourishing cycle business, with stores in Warri and Onitsha. At first he managed the bicycle section of his father's store: then he began trading on his own account, selling spare parts and, later, all makes of cycles. But the real turning point in his life came when he agreed to take part of a U.A.C. trader's allocation of Raleigh bicycles.



In 1953 Mr. Ezeli began to deal directly with The United Africa Company, and a year later he became a credit customer. Other assistance and good advice from the Managers enabled him to prosper, and today he has a large monthly turnover. He employs a salesman and three cycle-assemblers in his new stores at Warri who work with equipment supplied by the Company. His wealth proves the wisdom of his motto, "Work hard, specialise, and thoroughly understand your trade."



*Hundreds of African traders rely on The United Africa Company to bring them goods from all over the world—and many of them started successful businesses with stock supplied on credit by the Company, helped by advice from its Managers. To The United Africa Company every trader is an important source of information on the needs of African buyers, so that both the trader and the Company profit by their friendship in business together.*

*THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED*

# International Telephone Service Extension To Enugu and Kaduna

The Ministry of Communications and Aviation announces that the international telephone Service formerly restricted to Lagos and Ibadan, has now been extended also to all telephone subscribers in Enugu and Kaduna. Subscribers in any of these towns may now book international calls by asking the local operator for "International Service."

In all cases the minimum charge will be for a call of three minutes. A call of that duration to the United Kingdom would cost £3, and to the United States, Canada or Australia, £3. 15/- Further details about the charges to other countries are given in the preface to the Telephone Directory. there will be no necessity for deposits to be paid and the fees for international calls will be added to Subscribers' ordinary telephone accounts.

# Owo Te Ole To Ji Bata

(O bere loju ewe keji)

Sugbon eyiti Hausa yi se lotę yi ko nse ni arin mogalasi bi ko se larin gbangba odan. Bi a ti gbo oro na si niyi:-

Omokunrin Yoruba kan lo weran esin ni odan, nigbati bata nta a lese, o bo sile, o si ko dani. Orun ko sa mo iku, nigbati Yoruba na ntorugbe lo joko si egbe kan, o fori ti igi lo ba sun lo fonfon, o ko bata re si egbe re

Samo-samo, Hausa kan ti nso, bi o si ti sun lo beni Hausa na ki bata mole o si nlo kemo-kemo ni awon ti o ri i ba ji onibata pe enikan lo nko ra mu o di igbaju Pa a, bata re lo yen. O dide po o ni awon b a fa le o ki gbe ole ni awon ba olopa lowo.


# Freehold Houses For Sale

## ITIRE ROAD ESTATE SURU-LERE

NEWLY BUILT DETACHED FREEHOLD HOUSES (THREE AND FOUR ROOMS)

**Prices From £1,320**

OVER HALF THIS ESTATE HAS NOW BEEN SOLD
INSPECT SHOW HOUSES AT RACE COURSE
REASONABLE MORTGAGE TERMS ARRANGED
FULL DETAILS FROM:-

**Lagos Executive Development Board**
(ESTATE DEPARTMENT)
RECLAMATION ROAD, LAGOS.
TELEPHONE: 20384



Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS

*Read this list of popular titles*



HMV YELLOW & RED DOG
6098 - Kelegbe Megbe/Odun Titun Owo Titun
„6099 - Agba Olorin/Busura Baba Osa
„6100 - Yawa Yesu/Omolere Aiye
Jimo Ojindo
&

OBTAINABLE FROM:-
1. Y A Bilesanmi - 87 Victoria St, Lagos
2. Animawu Stores - 24 „ „ „
3. Salawu Aremu - 73 „ „ „

HMV BLUE DOG
J2A 100- Shogbola/Oluwa Gbawa Lowo Iku Ojiji
„ 101 Bakaro Alake/Ejire Baba Taju
„ 102 Raimi Oga Ota/Wahabi Baba Fasila
S. Aka & his (Sakara) Band

OBTAINABLE FROM:-
Omobori-Owo Stores
Lagos/Abeokuta

*Sold by all the best stores*

"HIS MASTER'S VOICE" Yellow Label RECORDS

HIS MASTER'S VOICE

THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED


Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street P.O. Box 467 Lagos Phone 23370